## Ina jo ọgbọn awọn alabaṣẹyẹ igbeyawo pa ni India

LUCKNOW-INDIA.

NI alẹ ọjọ 'Ru ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni ina ile-jijo kan ṣelẹ ninu ile ibiti nwọn gbe nṣe igbeyawo ni abule kan leti ilu Lucknow, ina si jo ọgbọn awọn alabaṣẹyẹ iyawo pa bamubamu.

Ijamba ina na ṣelẹ lati inu ile ise-onjẹ nibiti nwọn gbe se onjẹ ase adidun eyẹ igbeyawo ti o wa lẹgbẹ-ile oniyawo na. Nigbati ina ta mọ orile ibẹ ni o ba ta mọ ibiti nwọn ti nṣe igbeyawo gan an ni ọgbọ enia ba jona ku sibẹ.

Lọwọ iku ina. Oluwa rere gba wa.

# Obirin kan kọ ọkọ silẹ, nitoripe ọkọ na gun pupọ

IJUMU.

LENULỌLỌYI ni obirin abilekọ kan, Elizabeth Funmilayọ, ẹni ogun odun pe ọkọ rẹ, Ogbẹni M. Aleraiye lẹjọ niwaju Oloye Owonibi, Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Ijumu ni Ekinrin pe on fẹ lati kọ ọ silẹ: nitoripe o kun pupọ ju on lọ.

Ejọ ti obirin na lun ro ni pe koṣe ẹlọ si on o si nfi ebi pa on. O ni nigbati edeaiyede kan ba si ṣelẹ larin awọn nṣe ni o ma a nfi agbara rẹ le ori on ba ti i si ma a gbe on ṣanle bi ọmọde.

Ọkọ rẹ si sọ fun Adajọ pe, ọlẹ enia ni aya on na ati pe olẹ to bẹẹ gẹẹ ti ko le fi se onjẹ tabi se iṣẹ anfani kan. Adajọ na si gba pe ki nwọn kọ ara wọn silẹ, ki iyawo si san owo idana, pọnun metalelogun (£23) rẹ pada fun un.

## Adajọ sọ ọlọṣa sẹwọn oṣu mẹwa

MAKURDI.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Frade "B" Court) Makurdi sọ ọdaran kan, Iyodye Aji ẹni ọdun mejidinlọgbọn sẹwọn osu mẹwa nitoripe o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o ji Iyaafin Msenge Agbere ni orişirişi awọn ohun-elo ati aṣọ.



### AKIYESI FUN ONKAWE

Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin o n k a w e ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o ma a kọ o taara si ile iṣẹ rẹ ni :

Amalgamated Press Ltd.,
5/7, Apongbon Street,
P. O. Box 163, Lagos.



## Awọn ọmọde nyọ ayọ ajinde ninu omi-okun

EKO.

OJU ọgọrun awọn ọmọde lọ, t'ọkunrin t'obirin wọn ti nwọn nluwẹ ninu Omi-oku fun igbadun ajọyọ Ọdun Ajinde ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejidinlogun osu yi. Nitotọ nwọn ko wẹ jinna pupọ, bi Omi-okun ba ti nru-bọ ni nwọn ti nsa soke. Ere wọn na dun pupọ, ṣugbọn o mu ewu dani nitoripe 'Eiyẹ ogongo ni Omi-Okun, o kọja ohun ti a ra fun ọmọ de sere.' Ẹnyin obi ẹkilọ fun awọn ọmọ nyin o.

## Alimi Ọjẹyẹmi komọjade

ỌBAGUN LẸBA IKIRUN.

NI ọjọ Abameta ti nṣe ọjọ kokandinlogun oṣu t lo kọja yi ni Alimi Ọjẹyẹmi ṣe ikomọ jade ọmọ ti Ọlọrun fi ta on ati iyawo rẹ Rabi Agbekẹ lọrẹ. Nwọn si sọ ọmọ na ni Olufunmilayọ Adunni.

Awọn obi ọmọ na si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni:—Ogbeni A. Olowoyeye Babalọla, Alakoso oti Beer, Sunday Oyewọle, Karimu Akanni, Lasisi Ade. Olasco, Baka Ọlọpa, Ajiboye Okondoro, Jimọh Ojo, Buraimọh Dokun ati Ogbeni Tijani Ajibade.

Ki Oluwa da ọmọ na si o. Amin.



Aworan yi ni ti awọn ẹgbẹ oşişẹ ti Ogbẹni Imodu ọkan ninu awọn asiwaju ẹgbẹ oşişẹ ko lọ siwaju Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ni ọjọ 'Ru ti işe ogunjọ oşu yi ti nwọn lọ fi ibinu wọn han Ijọba pe a w ọ n tako didaduro ẹdẹgbasan (1,700) awọn oşişẹ ti nwa edu ni Enugu ti Ijọba fẹ da duro.



# FI WARAKASI SE ONJE TI O GBADUN NI KIAKIA

ẸNIKẸNI NI O FẸRAN RẸ LORI BURẸDI TABI AKARA-OYINBO

WARAKAŞI KRAFT ti şetan ni işẹju kan. Ẹnikẹni ninu awọn ẹbi rẹ ni o gbadun rẹ. O mbọ-ni-yo to bẹ ẹ gẹ ẹ. Fi warakaşi si ori burẹdi tabi akara-oyinbo fun awọn ọmọ rẹ nigbakugba ti ebi ba npa wọn. Warakaşi tete nse onjẹ kiakia fun gbogbo ẹbi rẹ pẹlu. Bere fun Warakaşi KRAFT ni ṣọbu itosi rẹ. O le ri i pẹlu irọrun ninu arẹwa agolo oni buluu ati yẹlo rẹ.




KRAFT FOODS LIMITED
Regina House, Marylebone Road, London N. W. 1.







Ebi ẹlẹja nfowo rẹ pamọ si

BARCLAYS BANK D.C.O.

Iwọ paapa le bẹrẹsi fi owo rẹ pamọ sibẹ loni.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Ẹgbẹ Young-Nur-Ud-Deen Society Mushin dupẹ lọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre



Eniti o joko ni arin ninu aworan yi ni Lemọmu-Agba Mọsalasi Jimọ Mushin. Ẹniti o duro ni ikangun apa-osi ni Mallam Arikewuyọ, akọwe eto ẹkọ. Ẹniti o duro ni ikangun apa-ọtun ni Ọgbẹni Alaṣiri, Akọwe-Agba.

* * * * * *

MUSHIN.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandilogun oṣu ti o kọja yi ni awọn Ẹgbẹ Young Nur-Ud-Deen Society ṣe Ipade pataki ni Obongan Apejọ Ijọba ibilẹ Mushin. Alfa Arikewuyọ Lemọmu Agba ni o ṣe alaga ipade na.

Idi ti nwọn pe ipade yi fun ni lati jiroro lori imọran bi awọn ọmọ Musulumi ti o wa ni Muhsin ati agbegbe rẹ yioti ṣe ni ilọsiwaju ninu ẹkọju ti atehinwa lọ. Ninu ipade na, nwọn si tun da ẹgbẹ titun kan silẹ ti nwọn pe ni:—"The Ikẹja Muslim Education Board".

Ohun pataki ti nwọn da ni imoran ninu ipade yi ni pe: o yẹ ki awọn da ile-iwe kekere ati giga silẹ fun ti awọn Musulumi ni Ikẹja ati agbegbe rẹ. Imoran keji si nipe: Lati fi si etigbọ Alamojuto Eto Ẹkọ (Local Eudcation Adviser) Ikẹja pe awọn nfẹ ki nwọn gba awọn oluko ti o jẹ Musulumi si awọn ile iwe ti o wa ni Ikẹja ati agbegbe rẹ, ki awọn ọmọ Musulumi ti o ba nkẹkọ ninu awọn ile iwe wọnyi le ni anfani lati le ni imọ ijinlẹ nipa ẹsin wọn.

Lẹhin ti nwọn ṣe eto yi tan, nwọn yan awọn Oloye Olori Lemomu Arikewuyọ ni alaga. Alufa S. Arikewuyọ (Akọwe) Alhaji Dabiri (alaga Eto Ẹkọ kikọ) Lemọmu Onibiyọ (Akapo).

Awọn enia pataki pataki ti o tun sọrọ nibi ipade yi ni Ọgbẹni Razack Ayanwale (Baba Ẹgbẹ Nur-Ud-Deen Mushin ati Iyaafin Anipele (Aṣiwaju Adini Mushin).

Ẹniti o mu imoran dida ẹgbẹ titun yi silẹ ninu ipade na ni Alufa Arikewuyọ, on na si ni o sọrọ gbẹhin. O si dupẹ lọwọ Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre fun eto ominira ẹkọ ti nwọn fi da awọn ọmọ Musulumi gbogbogboo lọla. O si tun ṣadura fun awọn Olotu Ijọba na pe ki Ọlọrun jẹki Ijọba nwọn fi ẹsẹ mulẹ lailai. Gbogbo awọn enia ti o pejọ sibi ipade yi si bẹrẹsi nyọmbo Oloye Awolọwọ ati Oloye Akintọla pe:— Awo! Awo!! SLA! SLA!! "AO on top".

Ki o to pari ọrọ rẹ o gba awọn ẹgbẹ titun na ni iyanju pe anfani ti awọn Ijọba Ọlẹpẹ fun wọn yi, o tọ, o si yẹ, pe ki gbogbo wọn lo o ni ọna ti o tọ. Nwọn mu ipade na wa si opin pẹlu adura.

## Adajọ tu ẹjọ idibo ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ pe ka

ABẸOKUTA.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ogunjọ oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Travers Charles, Adajọ Agba Kotu Nla Abẹokuta pa ẹjọ idibo ti Oloye J. O. Akande, ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) pe Ọmọ-ọba Adeniyi Adedamọla, ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group ti o moke ninu idibo Apapọ Ijọba Naijiria, o si ni ki Oloye Akande lọ san pọnun marunlelọgọrun (£105) owo irin-ẹsẹ fun Ọmọ-ọba Adeniyi Adedamọla.

Adajọ Agba na tun pa ẹjọ idibo ti Ọgbẹni S. A. Taiwo, ọmọ ẹgbẹ Alakukọ Ẹgbado pe Ọgbẹni D. K. Alhonsu, ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o moke ninu idibo Apapọ Ijọba Naijiria, o ni ki Ọgbẹni Taiwo lọ san pọnun marunlelọgọrun (£105) owo irin ẹsẹ fun Ọgbẹni Aihonsu. Adajọ si gba iṣẹsun ẹjọ ti awọn ti nwọn mba ṣe ẹjọ pe ọna aitọ ni nwọn si pe awọn lẹjọ. Adajọ na si ni nitotọ ọna ti nwọn gba fi pe ẹjọ wọnyi ki iṣe ọna ẹjọ'rara. Nitoria ni o ti ṣe da awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre mejeji lare.

## Adajọ sọ ọlọṣa kan sẹwọn ọdun marun

OYỌ.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni Oloye Adrew Thomas Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Grade "A" Customary Court) Oyọ sọ ọdaran ọdọmọkunrin kan, Mọmọh Mohatu sẹwọn ọdun marun: nitoriti o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba ṣe pe o lọ fọle Salau Adeoye ti o ngbe adugbo Ekinle, Iṣẹyin ni itosi Oyọ.

Ọdaran na sọ fun Adajọ pe iṣe ole ni on ṣe, on si jẹbi ẹjọ na ti awọn ọlọpa ba on ṣe ni Adajọ ba fi sọ ọ sẹwọn.

* * * *

Ni ọjọ kanna ni Adajọ kanna sọ ọdaran ọkunrin alainiṣẹ kan sẹwọn ọdun mẹta 'toripe o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o lọ ji Agnes Aiyeola kan ni pọnun mẹwa ni ọjọ kini oṣu yi.

## Adajọ sọ ẹniti o ji ewurẹ si ẹwọn ọdun meji

IJẸBU-ODE.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Ibilẹ Ijẹbu-Ode (Grade 'A' Customary Court) sọ ọkunrin ajiewurẹ gbe kan Sanni Bakare sẹwọn ọdun meji oniṣẹ aṣekara nitori o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi kan an pe o ji ewurẹ alabagbe rẹ kan Ọgbẹni Juadu Aṣiru gbe.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ro na ni wipe ọkunrin ọdaran na pa ewurẹ na o si gbe ru ọmọ rẹ obinrin Aduni Bakare ọmọ ọdun mejidinlogun pe ki nwọn o lọ ta a lọja. Ṣugbọn Adajọ da ọmọ na silẹ.

## Adajọ sọ 'onibara ọlọpa' sẹwọn oṣu mẹfa

IBADAN.

LẸNULỌLỌYI ni Adajọ Agba Kotu Kekere Ibadan sọ ọdaran kan, Sunday Ojẹdele, ẹni ọdun mejidilogbọn ti awọn ọlọpa pe ni 'onibara wa' sẹwọn oṣu mẹfa: nitoripe o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o ji obirin kan ti o nṣowo ni adugbo Agbeni ni apo owo ti pọnun mejila wa ninu rẹ.




DA
INU RIRUN
DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, ohun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe omiro ti pọju nibẹ....Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya. Ṣa ti mu egbogi Phillips' "Milk of Magnesia" diẹ . . . . yio si ko rirogun omiro na kuro, a si le irora na lọ werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara. Ko lewu, e roun lati lo, o si tu ni lara.

'MILK OF MAGNESIA'

AWỌN TI O NṢE E NI

PHILLIPS




O DARA FUN GBOGBO ẸBI

# Ẹgbẹ Ilọsiwaju Ilọra ṣẹyẹ fun Ọgbẹni Oyetayọ



Aworan yi ni Iyaafin Julianah Adeniran nigbati o nfi ẹbun aṣọ iyebiye fun Obinrin B. O. Eyitayọ

## AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọọ sowọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdalẹ Yoruba. A o si tẹẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU

# Aworan Odo ati ibi ẹyẹ isinku Obirin ti iwinlẹ-odo sọ di aabọ enia l'Aiyesan



Aworan awọn ti o nfi ọkọ-ajẹ ṣe ẹyẹ isinku Emma Takurọ leti odo ọfara l'Aiyesan.



Eyi ni aworan odo ọfara, bi obirin ti o joko ninu aworan yi ti nfọsọ ni Emma Takuro nfọsọ ki iwinlẹ-odo to wa ba nibẹ ki o to ma a fa lọ si isalẹ odo, ki o to ja ajẹbọ lọwọ iwinlẹ-odo ha



Aworan awọn ara ilu Aiyesan nigba ẹyẹ isinku Emma Takurọ lati odo ọfara



Aworan yi ni ti Iyaafin Sabainah ti o gba Emma Takuro Dilẹ lọwọ Iwin-odo Ọfara

# Onitẹtẹ fi igo pa onitẹtẹ ẹgbẹ rẹ

## Awọn Agba Ọrelu



## Egungun kan ku ni Kabba, nwọn tun ri i ni Gbede

## Obirin Abakaliki kan bi Ibeta

# AWORAN ONITAN



# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Apẹlẹwọn ti o gba idajọ ẹwọn dupẹ lọwọ Adajọ

BAUCHI.

LAIPẸYI ni ọdọmọkunrin ọdaran kan, Abudu Rama, ti awọn ọlọpa pe ni 'apẹlẹwọn' kunlẹ si Iwaju Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Alikali) Bauchi o si ni 'a dupe' nigbati Adajọ na sọ ọ sẹwọn oṣu mẹfa: nitoriti o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o lọ ji ọkunrin kan Usuman Bauchi ni ṣile mẹjọ (8s.).

Bi ẹjọ na ti ṣe lọ si ni pe, nigbati ọdaran na lọ ki Usman Bauchi ni ọja nibiti o gbe nta ọja rẹ ni o ba fi ji ṣile mẹjọ (8s.) na.

* * * *

Adajọ na tun sọ ọdaran kan, Daniadi sẹwọn nitoriti o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o wọ inu ile kan lọ lati jale. O si tun ṣe idajọ fun awọn ọdaran mẹwa kan pe, ki ọkọọkan wọn lọ fi pọnun kan tanran nitoripe wọn jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba wọn pe, ole ati isansa ni wọn.

## Adajọ sọ akọwe Shell-BP ti o jale sẹwọn oṣu mejila

OWERRI.

LẸNULỌLỌYI ni Adajọ Kotu Kekere Owerri sọ ọdaran kan,Douglas Onwuke, ẹni ọdun mẹtadinlọgbọn, akọwe alamojuto alafia awọn Oyinbo Onisọwo Shell-BP Company' ti o si ngba pọnun marundinlogoji ati ṣile marun (£35. 5s.) loṣu sẹwọn oṣu mejila: nitoriti o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe.

Ẹsun marun ni ọna olejija ati yiyiwe-pada ni ọna eru ni awọn ọlọpa ka si ọdaran na lọrun, ṣugbọn Adajọ da a silẹ ninu mẹrin, o ni ko jẹbi, o s isọ ọ sẹwọn fun ti ẹkarun ti nwọn ka si i lọrun pe, oji awọn oga iṣẹ rẹ ni apoti ọti bia mẹtadinladọrin (83) ti aropọ iye owo wọn jẹ pọnun mẹtaleladọta-le ni irinwo ati ṣile meji din kẹbọ (£453. 1s. 11d.).

Ọdaran na sọ fun Adajọ pe on ko jẹbi, on yio si pe ẹjọ kotẹmilọrun. Ki nwọn si to gba iduro rẹ, o fi igba pọnun (£200) ati oniduro kan ti o fi ọwọ si iwe iye owo kanna (£200) niwaju Adajọ dogo.

## Adajọ ni ki ọlọti bọlugi lọ fi £20 tanran

ABA.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Aba ni k lọdaran kan, Eze-Enyelugo t'o nṣiṣẹ agbẹ lọ fi ogun pọnun (£20,000) tanran tabi ki o lọ ṣe ẹwọn oṣu meji, nitoripe o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe awọn ka galọnu ọti bọlugi mọ lọwọ.

Ọdaran na sọ fun Adajọ pe on jẹbi. O ni ọrẹ on kan ti on ti gbagbe orukọ rẹ ni o fun on ni ọti na ni Adajọ na fi ni ki o lọ fi owo tanran tabi ki o lọ ṣe ẹwọn.

## Ole gbe onisọwo malu ni £3000 salọ

UMAHIA.

LẸNULỌLỌYI ni awọn ole gbe Hausa onisọwo malu kan ni ẹgbẹdogun pọnun (£3.000) lọ, awọn ọlọpanu si ti bẹrẹsi si wa ole na lati mu u, nwọn koi ti ri




